Àkópọ̀ Ìkéde Àṣà Ìṣọ́ Àṣírí
(Summary of Notice of Privacy Practices)

Bẹ̀rẹ̀: Láti Ẹnu April 13,2003
Àtúwò ni: Osu March 5, 2026

A mọ̀ pé àlàyé nípa ìlera rẹ jẹ́ ohun tí ó kan ọ lára gidigidi, àti pé a ti pinnu láti dáàbò bo àṣírí rẹ. Ìkéde àkópọ̀ yìí je ranpe kí ó lè rọrùn láti lòye. Ìkéde kíkún nípa àṣà síṣọ àṣírí tún wà fún ọ lójú ìkànnì wẹ́ẹ̀bù wa àti ní àwọn àgbègbè ìtọ́jú wa.

Ìkéde yìí ṣàpèjúwe bí àlàyé ìṣègùn nípa rẹ ṣe lè ní ìlò àti pínpín, àti bí o ṣe lè gba ànfààní láti ni pin sí àlàyé yìí. Jọwọ́ ṣàyẹ̀wò rẹ̀ dáradára.

Fún apá kejì (2) àwọn àkọsílẹ̀ ìṣòro lílo ohun àìjípépé, ìkéde yìí ṣàpèjúwe:

- Bí àlàyé ìlera apá (2) nípa rẹ ṣe lè ní ìlò àti ṣíṣé àfihàn
- Àwọn ẹ̀tọ́ rẹ tó jẹmọ́ àlàyé ìlera rẹ
- Bí a ṣe lè fi ẹ̀sùn kan nípa ìrúfin ìpamọ́ tàbí ààbò ìwífún nípa ìlera rẹ, tàbí ẹ̀tọ́ rẹ nípa ìwífún rẹ

O ní ẹ̀tọ́ láti gba àdàkọ ìwífún yìí (nínú ìwé tàbí fọ́ọ̀mù oníná) àti láti bá òṣìṣẹ́ ìpamọ́ wa sọ̀rọ̀] ní 833-718-1043 tàbí privacyofficer@trinity-health.org tí o bá ní ìbéèrè èyíkéyìí.

**Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ**

O ní ẹ̀tọ́ láti:

- Gba ẹ̀dà àkọsílẹ̀ ìṣègùn rẹ tó le wà nínú ìwé tàbí ẹ̀rọ àtẹ̀jísé
- Ṣe àtúnṣe àkọsílẹ̀ ìṣègùn rẹ tó wà nínú ìwé tàbí ẹ̀rọ àtẹ̀jísé
- Béèrè fún ìsọ̀rọ̀ àṣírí
- Beèrè lọ́wọ́ wa láti dín àlàyé tí a pín kù
- Gba àtòjọ àwọn ẹni tí a ti pín àlàyé rẹ pẹ̀lú wọn- Ìṣirò Àwọn Àfihàn
- Gba ẹ̀dà ìkéde àṣírí yìí
- Yan ẹnìkan láti ṣe aṣojú rẹ
- Fi ẹ̀sùn kàn tí o bá gbàgbọ́ pé àwọn ẹ̀tọ́ àṣírí rẹ ti jẹ rìrù

**Àwọn Àsàyàn Rẹ**

O ní àwọn àsàyàn kan nípa ọ̀nà tí a ń lò àti pínpín àlàyé bí a ṣe ń:

- Sọ fún ẹbí àti àwọn ọ̀rẹ́ nípa ipò ìlera rẹ
- Pèsè ìrànlọ́wọ́ ìdásí ajálù
- Ṣàkọsílẹ̀ rẹ nínú àtòjọ ilé ìwòsàn
- Pèsè ìtọ́jú ìlera ọpọlọ
- Ṣe ìpolongo àwọn iṣẹ́ wa àti tà àlàyé rẹ
- Kó owó jọ

**Báwo ni a ṣe ń lò tàbí pín àlàyé ìlera rẹ ní ìgbà gbogbo?**

A sábà máa ń lò tàbí pín àlàyé ìlera rẹ ní àwọn ọ̀nà wọ̀nyí.

**Tọ́ jú rẹ**

A lè lò àlàyé ìlera rẹ àti pín rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ẹlòmíràn tí wọn ń tọ́jú rẹ.

Ìkéde yìí bo gbogbo àwọn ibi ìtọ́jú pẹ̀lú àwọn ilé ìwòsàn, àwọn ilé ìwòsàn kékeré àti ìtọ́jú ìṣòro lílo ohun áìjípépé, èyí tí a ń pè ní Ètò Apá Kejì (2).

A pèsè ìtọ́jú ìṣègùn àti pé a ní àwọn ètò ìtọ́jú ìṣòro lílo ohun áìjípépé tí àwọn òfin Àpapọ̀ tó wà nínú 42 CFR Apá Kejì (2) ń bójú tó (tí a ń pè ní Ètò "Apá Kejì 2"). Tí o bá gba irú ìtọ́jú yìí, a lè béèrè lọ́wọ́ rẹ láti fọwọ́ sí fọ́ọ̀mù àṣẹ gbogbogbò fún ìtọ́jú fún Ètò part 2. Àṣẹ tí a kọ fún àwọn ìtọ́jú, ìsan-owó àti ìṣàkóso lè gba ẹ̀ẹ̀kan ṣoṣo àti lè ṣe àtìlẹyìn fún àwọn lílo àlàyé ìlera ni ojo waju fun itọ́jú, ìsan-owó, àti ìṣàkóso láìsí àṣẹ àfikún lábẹ́ HIPAA.

**Ṣe ìṣàkóso ilésé wa**

A lè lo àti pín àlàyé ìlera rẹ láti ṣe ìṣàkóso ètò ìlera wa, mú ìtọ́jú rẹ dára sí i, àti kàn sí ọ nígbà tí ó bá pọndandan.

A ń lo ìmọ̀-ẹ̀rọ láti ṣe àtìlẹyìn fún ìtọ́jú àti ìṣègùn tí ó lè lo Oye Atọwọdá (AI). Ìmọ̀-ẹ̀rọ oye atọwọdá ń lo àlàyé ìlera láti kọ àti mú ìṣiṣẹ́ oye atọwọdá dára sí i. Àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ ìmọ̀-ẹ̀rọ wa, títí kan àwọn tí ó ní ìmọ̀-ẹ̀rọ oye atọwọdá, gbọdọ̀ pa àlàyé ìlera mọ́ nínú àṣírí gẹ́gẹ́ bí òfin tó wọn.

**Àgbéjáde Ìwé Ìsan-owó Fún Àwọn Iṣẹ́ Rẹ:** A lè lo àti pín àlàyé ìlera rẹ láti ṣe àgbéjáde ìwé ìsan-owó àti gba ìsan-owó láti ọwọ́ àwọn ètò ìlera tàbí àwọn àjọ míràn.

**Ònà míràn wo ni a se lè Lo tàbí pín àlàyé ìlera rẹ?**

A gbà wá láyè tàbí a nílò pé kí a pín àlàyé ìlera rẹ ní àwọn ọ̀nà míràn - ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ní àwọn ọ̀nà tí ó ń ṣe àfikún sí rere àwùjọ, bí ìlera àwùjọ àti ìwádìí. A gbọdọ̀ de àwọn ipò àkànṣe tí òfin pèsè ṣáájú kí a tó lè pín àlàyé rẹ fún àwọn ète wọ̀nyí.

**Ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn ìṣòro ìlera àti ààbò àwùjọ:** A lè pín àlàyé ìlera nípa rẹ fún àwọn ipò àkànṣe bí:

- Ídènà àrùn
- Ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn ìpàdépadà ọjà
- Ìjábọ̀ àwọn èsì ìpalára sí àwọn oogun
- Ìjábọ̀ Ìfura si àbùkù, ìpanitì, tàbí Ìwà Ipá Inú Ilé
- Ídènà tàbí àdínkù ewu tó le koko je sí Ìlera tàbí Ààbò Ẹnikẹ́ni

**Ṣe Ìwádìí:** A lè lo tàbí pín àlàyé rẹ fún ìwádìí ìlera.

**Tẹ̀lé Òfin:** A óò pín àlàyé nípa rẹ tí àwọn òfin ìpínlẹ̀ tàbí àpapọ̀ bá nílò rẹ̀, títí kan pẹ̀lú Ẹ̀ka Ìlera àti Iṣẹ́ Ènìyàn tí ó bá fẹ́ ríi dájú pé a ń tẹ̀lé òfin àṣírí àpapọ̀.

**Fèsì sí Àwọn Ìbéèrè Ẹ̀bùn Ẹ̀yà ara:** A lè pín àlàyé ìlera nípa rẹ pẹ̀lú àwọn àjọ tí ń gba àwọn ẹ̀yà ara.

**Ṣiṣẹ́ pẹ̀lú Aṣàyẹ̀wò Ìṣègùn tàbí Olùdarí Ìsìn Òkú:** A lè pín àlàyé ìlera pẹ̀lú olùṣèwádìí ikú, aṣàyẹ̀wò ìṣègùn, tàbí olùdarí ìsìn òkú nígbà tí ẹni kọ̀ọ̀kan bá kú.

**Àṣedánwò Òṣìṣẹ́, Ìmúlò Òfin, àti Àwọn Ìbéèrè Ìjọba Míràn:** A lè lo tàbí pín àlàyé ìlera nípa rẹ:

- Fún àwọn ẹtọ àṣedánwò àwọn òṣìṣẹ́ tí wọ́n farapa lénu iṣẹ́
- Fún àwọn ìmúlò òfin tàbí pẹ̀lú olúṣọ òfin
- Pẹ̀lú àwọn àgbádúró ìlera fún àwọn iṣẹ́ tí òfin fún níṣẹ̀
- Fún àwọn iṣẹ́ ìjọba àkànṣe bí àwọn iṣẹ́ ológun, ààbò orílẹ̀-èdè, àti àwọn iṣẹ́ ààbò Ààrẹ

**Fèsì sí àwọn ẹjọ́ ilé-ẹjọ́ àti àwọn ìgbésẹ̀ òfin**

- A lè pín àlàyé ìlera nípa rẹ nígbà tí a bá fèsì sí àṣẹ ilé-ẹjọ́ tàbí àṣẹ ìṣàkóso, tàbí nígbà tí a bá fèsì sí ìpè ẹjọ́
- Tí a bá ní àwọn àkọsílẹ̀ aláìsàn tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìlòkulò ohun amúnisìn nípa rẹ, tí ó wà lábẹ́ 42 CFR part 2, a kò lè lo tàbí pín àlàyé tí ó wà nínú àwọn àkọsílẹ̀ wọ̀nyẹn nínú àwọn ìwádìí tàbí ìgbẹ́jọ́ aráàlú, ọ̀daràn, ìṣàkóso, tàbí àṣofin tí a ṣe lòdì sí ọ láìsí (1) àṣẹ rẹ tàbí (2) àṣẹ ilé-ẹjọ́ àti ìpè ẹjọ́

**Àwọn Ojúṣe Wa**

- Òfin nílò pé a gbọdọ̀ ṣetọ́jú ìkọ̀kọ̀ àti ààbò àlàyé ìlera rẹ tí ó wà lábẹ́ ìdáàbòbò
- A óò jẹ́ kí o mọ̀ tí ìlọ́wọ̀sí aláìláṣẹ bá ṣẹlẹ̀ tí ó lè ti ru ìkọ̀kọ̀ tàbí ààbò àlàyé rẹ
- A gbọdọ̀ tẹ̀lé àwọn ojúṣe àti àwọn ìlànà ìkọ̀kọ̀ tí àpèjúwe nínú Ìkọ̀ròpọ̀ yìí àti ki a fún ọ ní ẹ̀dà rẹ̀
- A kò ní lo tàbí pín àlàyé rẹ yàtọ̀ sí bí a ṣe ṣàpèjúwe rẹ̀ nínú Ìkọ̀ròpọ̀ yìí àfi tí o bá sọ fún wa à pé a lè ṣe bẹ́ẹ̀ nípa kíkọ. Tí o bá sọ fún wa pé a lè ṣe bẹ́ẹ̀, o lè yí èrò rẹ padà nígbàkúgbà. Jẹ́ kí a mọ̀ nípa kíkọ àtèjísé tí o bá yí èrò rẹ padà

**Àwọn Iyípadà Sí Àwọn Ìlànà Ìkọ̀ròpọ̀ Yìí**

A lè yí àwọn ìlànà Ìkọ̀ròpọ̀ yìí padà, àti pé àwọn iyípadà náà yóò kan gbogbo àlàyé tí a ní nípa rẹ. Ìkọ̀ròpọ̀ tuntun náà yóò wà nígbà tí a bá béèrè fún un, ní àwọn àgbègbè ìtọ́jú wa, àti lórí ojú-ìwé wẹ́ẹ̀bù wa.

**Òfin Ìpínlẹ̀ àti Àpapọ̀ Tó Mọ́ Jù:** To òfin ìkọ̀kọ̀ kan bá wọ̀n, tí ó sì mọ́ jù HIPAA lọ, a óò tẹ̀lé e.

**Pàṣípààrọ̀ Àlàyé Ìlera ("HIE"):** Tí ó bá wà, a óò pín àlàyé ìlera rẹ pẹ̀lú Pàṣípààrọ̀ Àlàyé Ìlera láti pín pẹ̀lú àwọn olùpèsè ìtọ́jú míràn. Àlàyé ìlera rẹ lè ní àwọn àlàyé àìtọ́kasí nínú. HIE yóò ránṣẹ́ àti tọ́jú àlàyé ìlera rẹ. HIE gbọdọ̀ dáàbò bo àlàyé ìlera rẹ. Òfin ìpínlẹ̀ lè jẹ́ kí o yọ ara rẹ kúrò nínú HIE. Fún àlàyé síi, jọ̀wọ́ kan sí Olùṣọ Àkọsílẹ̀ Ìkọ̀kọ̀ wa nípa pípe 833-718-1043 tàbí nípa rírànṣẹ́ ìméèlì sí privacyofficer@trinity-health.org.

**Pípin àti Lílo Àlàyé Ìlera Rẹ:** Láti ràn wá lọ́wọ́ láti mú ìtọ́jú rẹ dára sí i, a lè pín àlàyé ìlera rẹ pẹ̀lú àwọn ẹlòmíràn. Trinity Health jẹ́ ètò ìlera Kátólíìkì orílẹ̀-èdè kan, èyí tó pẹ̀lú àwọn ilé-ìwòsàn míràn, àwọn ilé ìtọ́jú àgbàlagbà, àti àwọn olùpèsè ìlera. A ń pín àlàyé ìlera rẹ láti ṣakoórí ìtọ́jú rẹ pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ ìwòsàn àti òwò míràn tí Trinity Health ń ṣe.

- Àwọn Oníṣẹ́ Ìlera: A wà nínú Ètò Ìlera Tó Ṣètò ("OHCA") pẹ̀lú àwọn oníṣẹ́ ìlera. Èyí túmọ̀ sí pé a pín àlàyé ìlera pẹ̀lú àwọn oníṣẹ́ ìlera fún àwọn iṣẹ́ àti ìmúṣẹ ètò. Ó tún túmọ̀ sí pé àwọn oníṣẹ́ ìlera ti gbà láti tẹ̀lé àwọn ìlànà tó wà nínú Ìkọ̀ròpọ̀ yìí

- Àwọn Alábàáṣiṣẹ́pọ̀ Òwò: A lè pín àlàyé ìlera pẹ̀lú àwọn ilé-iṣẹ́ míràn gẹ́gẹ́ bí apá kan àwọn iṣẹ́ òwò wa

**Àwọn Ẹjọ́ Ìfẹ̀sùn:** Tí o bá gbàgbọ́ pé a ti ru àwọn ẹ̀tọ́ ìkọ̀kọ̀ rẹ, o lè ṣeébọ ẹjọ́ kan sí Olùṣọ Àkọsílẹ̀ Ìkọ̀kọ̀ wa tàbí sí Akọ̀wé Ìjọba Ẹ̀ka Ìlera àti Iṣẹ́ Ènìyàn. Ẹ lè fi ẹjọ́ àwọn ìfẹ̀sùn hàn sí wa nípa lílo àdírẹ́sì ìméèlì privacyofficer@trinity-health.org, tàbí nípa pípe wa lórí 833-718-1043, tàbí nípa kikọ lọ sí olùṣọ àkọsílẹ̀ ìkọ̀kọ̀ ètò wa ní: 20555 Victor Parkway, Livonia, MI 48152.

*Kò ní sí ìgbẹ̀san sí ọ fún ìgbésẹ̀ tí o bá ṣe láti ṣeébọ ẹjọ́ èyíkéyìí.*